**ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU**

Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.

**ÈTÒ ÌPÀDÉ AGBÁRA GBỌ́DỌ̀ PÀRỌ̀ ỌWỌ́**

**DÍDÒJÚKỌ ÀWỌN Ẹ̀MÍ ÒKÙNKÙN ÀJÀKÁLẸ̀-ÀRÙN TÓKÁRÍ AYÉ (3)**

**OṢÙ KÁRÙN 2022**

Ìwé Mímọ́ kíkà: Orin Dáfídì 17; 27; 91

Ìjẹ́wọ́: Orin Dáfídì 91

## ORIN ÌYÌN ÀTI ÌJỌ́SÌN TÍ Ó L'ÁGBÁRA

1. Ọlọ́run, dìde, kí Ó sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn sínú Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìṣọ́ji, bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Ọlọ́run, jẹ́ kí agbára àláfíà àti itẹ̀síwájú, ṣíji bo orílẹ̀-èdè yìí, ní orúkọ Jésù.
4. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fún wa ní àwọn olórí tó bẹ̀rù Ọlọ́run, ní orúkọ Jésù.
5. Àwọn agbára tó gbé ìdótì dìde lòdì sí ìlera mi, wó lulẹ̀, ko sì kú, ní orúkọ Jésù.
6. Àwọn agbára àjàkálẹ̀-àrùn tókárí ayé, tí ọ̀tá nlò láti halẹ̀ mọ́ mi, wó lulẹ̀, ko sì kú, ní orúkọ Jésù.
7. Gbogbo agbára ìnilára àti agbára ẹ̀rù tí àjàkálẹ̀-àrùn tókárí ayé ru sókè lòdì sí ayé mi, mo fà ọ́ lulẹ̀, ní orúkọ Jésù.
8. Gbogbo ọwọ́ ìnilára tí a nà sími, gbẹ, ní orúkọ Jésù.
9. Gbogbo ẹnu aninilára tó n sọ̀rọ̀ lòdì sí ìlera mi, panumọ́, ko sì kú, ní orúkọ Jésù.
10. Ohun rere ìyówù tí àjàkálẹ̀-àrùn tókárí ayé jí mọ́mi lọ́wọ́, mo gbà á padà ní ìlọpo méje, ní orúkọ Jésù.
11. Àwọn ẹ̀mí òkùnkùn mùjẹ̀-mùjẹ̀, tí àjàkálẹ̀-àrùn tókárí ayé ru sókè, èmi kì í ṣe èrò rẹ, padà síbi toti wá, ní orúkọ Jésù.
12. Ohun ìyówù tó nbẹ láyé, bẹ lááyè, tó n ni ọjọ́ iwájú mi lára, Olúwa, gé wọn dànù, ní orúkọ Jésù.
13. Nípa agbára tówà nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù, jẹ́ kí gbogbo ẹ̀mí aìmọ́ tí ó ni í ṣe pẹ̀lú àjàkálẹ̀-àrùn tókárí ayé yìí, tó ti wọnú mi lọ, kú, ní orúkọ Jésù.
14. Gbogbo ọfà àjàkálẹ̀-àrùn tókárí ayé tí wọ́n yàn láti pa àwọn ibùkún mi, kú, ní orúkọ Jésù.
15. Àwọn ogun tí àjàkálẹ̀-àrùn tókárí ayé yàn láti dí ọ̀nà mi, túká, ní orúkọ Jésù.
16. Ẹ̀jẹ̀ ìrékọjá Jésù, dábóbò ibùgbé mi nípa iná, ní orúkọ Jésù.
17. Ìpọ́njú àjàkálẹ̀-àrùn tókárí ayé ìyówù, tí wọ́n yàn láti fi oúnjẹ àwọn ọ̀tá bọ́ mi, kú, ní orúkọ Jésù.

18. Gbogbo ogun tóti ipasẹ̀ àjàkálẹ̀-àrùn tókárí ayé dìde, tí wọ́n yàn láti ba idùnú mi jẹ́, túká nípa iná, ní orúkọ Jésù.
19. Agbára ìyówù tó ti ipasẹ̀ àjàkálẹ̀-àrùn tókárí ayé jẹyọ, tó fẹ́ kí n ma gbé gẹ́gẹ́ bí òkú ènìyàn, kú, ní orúkọ Jésù.
20. Gbogbo omi tó n bẹ nínú àgọ́ ara mi, gbé iná Ẹ̀mí Mímọ́, ko sì pa gbogbo irúgbìn àilera run, ní orúkọ Jésù.
21. Ìwọ ibi gíga àti ọkùnrin alágbára àjàkálẹ̀-àrùn tókárí ayé yìí, èmi kì í ṣe èrò rẹ, mo gbé ọ sin báyìí, ní orúkọ Jésù.
22. Ẹ̀jẹ̀ Jésù, dìde, fọ gbogbo májèlé àjàkálẹ̀-àrùn tókárí ayé kúrò nínú ara mi, ní orúkọ Jésù.
23. Àwọn agbára àjàkálẹ̀-àrùn tókárí ayé tó n gbé nkan mì, gbọ́ ọ̀rọ̀ Olúwa, pọ̀ mí jáde, ní orúkọ Jésù.
24. Gbogbo akitiyan àwọn afi kẹ́lẹ́-kẹ́lẹ́ bati ẹni jẹ́ lágọ̀ ara mi àti ní agbègbè mi, ṣègbé, ní orúkọ Jésù.
25. Àwọn drágónì tóti ìlà-òòrùn wa, èmi kì í ṣe èrò rẹ, gbá dànù, ní orúkọ Jésù.
26. Gbogbo agbára tí àjàkálẹ̀-àrùn tókárí ayé ru sókè láti jẹ ẹran ara àti láti mu ẹ̀jẹ̀ ara mi, kú, ní orúkọ Jésù.
27. Ejò àjàkálẹ̀-àrùn tókárí ayé agbègbè, ká kúrò lọ́dọ̀ mi, ní orúkọ Jésù.
28. Ìwọ ìbíkìbí àjèjì, tí àjàkálẹ̀-àrùn tókárí ayé bí, èmi kì í ṣe èrò rẹ, kú, ní orúkọ Jésù.
29. Mo fà lúlẹ̀, gbogbo ibi gíga, tí àjàkálẹ̀-àrùn tókárí ayé gbé dìde lòdì símì, ní orúkọ Jésù.
30. Ètò ìpọ́njú tí àjàkálẹ̀-àrùn tókárí ayé ru sókè, èmi kì í ṣe èrò rẹ, kú, ní orúkọ Jésù.
31. Ẹ̀jẹ̀ Jésù, pa gbogbo ìránṣẹ́ àilera, ní orúkọ Jésù.
32. Gbogbo ohùn àjàkálẹ̀-àrùn tókárí ayé, tó n rúnú lòdì sí ìpele mi tó kàn, kú, ní orúkọ Jésù.
33. Ibi ìyówù tí àwọn ẹ̀mí òkùnkùn àjàkálẹ̀-àrùn tókárí ayé kórajọpọ̀ sí, iná Ẹ̀mí Mímọ́, tú wọn ká, ní orúkọ Jésù.
34. Gbogbo ibojì àjàkálẹ̀-àrùn tókárí ayé, èmi kì í ṣe èrò rẹ, panumọ́, ní orúkọ Jésù.
35. Àwọn anfàní tí àjàkálẹ̀-àrùn tókárí ayé yì ti fi ṣòfò, mo gbà wọ́n padà nípa iná, ní orúkọ Jésù.
36. Àwọn ejò àti àkekè àjàkálẹ̀-àrùn tókárí ayé yìí, gbiná, ní orúkọ Jésù.
37. Ìdè tó ní í ṣe pẹ̀lú àjàkálẹ̀-àrùn tókárí ayé yìí, èmi kì í ṣe èrò rẹ, túká, ní orúkọ Jésù.
38. Gbogbo ẹ̀jẹ̀ búburú tó n sọ̀rọ̀ lòdì sí ayé mi nípa àjàkálẹ̀-àrùn tókárí ayé yii, ẹ̀jẹ̀ Jésù, tú wọn ká, ní orúkọ Jésù.
39. Gbogbo agbára atúnídanù àti olùdènà, tí ó sopọ̀ mọ́ àjàkálẹ̀-àrùn tókárí ayé yìí, fọ́ dànù, ní orúkọ Jésù.
40. Mo gbá dànù, gbogbo ibànújẹ́ tí ó sopọ̀ mọ́ àjàkálẹ̀-àrùn tókárí ayé yìí, ní orúkọ Jésù.